# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 567 MONDAY, MARCH 30, 1964 (2D)


## Ọdaran Ọlọpa Kan Lu Alagbafọ Pa

ABA :— Ọrọ di pọọntuka nigbati awọn ọlọpa meji kan bẹrẹ si iba ọkunrin kan Ọgbẹni Ukonu Eggute ẹni ọdun mejilelọgbọn ti o nṣiṣẹ alagbafọ wọ ijakadi pe ki o kalọ si Tesan ti nwọn si lu Ọkunrin na bi ẹjọ aijẹ lojukanna ni alagbafọ na ba ta teru nipa ni ọjọ kẹsan oṣu keje ọdun ti o kọja yi ti gbo gbo awọn ero iworan si tuka yangan mọ awọn Ọlọpa na lori.

Ọkan ninu awọn ọdaran ọlọpa na ṣe alaye fun oniwe Irohin wa wipe awọn mu alagbafọ na nitori ẹṣẹ kan ti o ti ṣe pe ki o ba awọn kalọ si Teṣan. Ṣugbọn alagbafọ na kọ o ni on ko ni lọ, ni awọn ba sọ wipe, "Ijọba npe ọ, o ni o ngmu gari, talo ni omi talọ ni gari ti o ngmu ?" Njẹ ti ko ba ṣe gbe yio ṣee wọ, ni awọn ba nwọ Ọkunrin na ni Olokuakitan.

Lẹsẹkẹsẹ ni gbogbo enia ba wa pari jọ le awọn lori, ṣugbọn nibiti awọn ti nṣe eyi lọwọ ni Ọkunrin na ba ku mọ awọn lọwọ, ti gbogbo awọn ero iwosan si tuka mọ awọn lori.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn Ọlọpa na ba gbe oku alagbafọ na lọ si Ile Iwosan fun ayẹwo awọn Dokita nwọn si ti awọn Ọlọpa na mọle.

Ninu ẹsẹ yi ni ibayọri ayẹwo awọn Dokita to jade Dokita na sọ wipe pẹlu ipa ati agbara ti awọn Ọlọpa fi mu ọkunrin na pẹlu lilu ti nwọn tun lu bi gudasi ni o pa ọkunrin na.

A gbọ wipe awọn ọdaran Ọlọpa mejeji yio farahan niwaju adajọ ni owurọ yi lati sọ ti ẹnu wọn.

Bi nwọn ba si ti pari ọrọ na si, ẹ o un ma a gbọ o.

# ALAFIA FUN NYIN!

Li opin ọjọ Isimi, ibi ilẹ ọjọ kini ọsẹ ti bẹrẹsi imọ, Maria Magdalene ati Maria keji wa lati wo iboji na. Si kiyesi o, isẹlẹ nla ṣẹ, nitori angẹli Oluwa ti ọrun sọkalẹ wa, o si yi okuta na kuro, O si joko le e; oju rẹ dabi manamana, aṣọ rẹ si funfun bi ẹgbọn owu. Nitori ẹru rẹ, awọn Olusọ wariri, nwọn si dabi oku.

Angẹli na si dahun, o si wi fun awọn Obinrin na pe, "Ẹ ma bẹru, nitori emi mọ pe ẹnyin nwa Jesu, ti a ti kan mọ Agbelebu, ko si nihinyi nitori o ti jinde gẹgẹbi o ti wi.

Wa, wo ibiti Oluwa ti dubulẹ si. Ẹ si yara lọ sọ fun awọn ọmọ-ẹhin Rẹ pe o ti jinde kuro ninu oku, "Wo o, o saju nyin lọ si Galili nibẹ li ẹnyin o gbe ri i, Wo o, mo ti sọ fun yin.

Nwọn si fi ibẹru pẹlu ayọ nla yara lọ kuro ni iboji, nwọn si sare lọ rohin fun awọn ọmọ ẹhin Rẹ. Bi nwọn si ti nlọ sọ fun awọn ọmọ ẹhin rẹ, woo, Jesu pade wọn. O wipe "Alafia".



Nwọn si wa, nwọn si gba A ...li ẹsẹ mu, nwọn si tẹriba fun un. Nigbana ni Jesu wi fun wọn pe, "Ẹ ma bẹru, ẹ lọ sọ fun awọn arakunrin mi pe, ki nwọn ki o lọ si Galili, nibẹ ni nwọn o gbe ri mi"

Nigbana li awọn ọmọ ẹhin rẹ mọkanla jade lọ si Galili, si ori Oke ti Jesu ti sọ fun wọn. Nigbati nwọn si ri I, nwọn foribalẹ fun un, ṣugbọn awọn miran ṣiyemeji Jesu si wa, o si sọ fun wọn wipe,

'Gbogbo agbara li ọrun ati li aiye li a ti fi fun mi. Nitori na, ẹ lọ, ẹ ma a kọ Orilẹ-ede gbogbo, ki ẹ si ma a Baptist wọn li oruko Baba ati ni ti Ọmọ, ati ni ti Ẹmi Mimọ.

Ki ẹ ma a kọ wọn lati ma a kiyesi ohun gbogbo, ohunkohun ti mo ti pa li aṣẹ fun nyin, ẹ si kiyesi i, emi wa pẹlu nyin nigbagbogbo ti o fi de opin aiye Amin.

Ẹ ku ọdun, ẹ ku iyedun o

Ka ọrọ Olotu ni oju ewe keji.


WA WO ERE

**Ọlaọrẹ Afọtẹjoye**

NI

**Methodist Boys' High School, Eko**

Ni 30/3/64. Ni agogo Meje Abọ Irọlẹ


## Akiyesi

A fẹ ki awọn Onibara wa ma a san owo si apo wa deede, ẹniti ko ba san owo tirẹ, ki o ma ya a lẹnu bi a ba da a duro lojiji, ao si gba owo wa lọwọ rẹ.

Ẹ ku iṣẹ o.

**Olotu**

# IROHIN IMOLE

ESIN-ORO WA - IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA
Ẹ kowe si:— OLOTU IROHIN IMOLE

FUN OWO IROHIN IMOLE ODUN KAN
PONUN MEJI ṢILE MEJILA (52/-)


## ỌRỌ OLOTU

## Kristi Jinde! Alleluyah!

Pẹlu ayọ ati inu didun ni awa oniwe irohin Imọlẹ fi ki gbogbo ẹnyin onkawe wa ku ewu ọdun Ajinde yi. A dupẹ lọwọ Ọlọrun ti o da emi wa si lati tun pelu wọn ṣe ọdun ayọ. Ki Ọlọrun Olodumare Ọba ti o fẹ wa ju bi a ti feran ara wa lọ da ẹmi gbogbo wa si, ki a si le ṣe ọpọlọpọ ọdun l'aiye.

A fẹ ran nyin leti pe bi a ti nṣe ọdun Ajinde yi, ti gbogbo rẹ si ndun yungba-yungba ti ilu ndun lọtun losi, ti aṣe apejẹ ati apemu nsọlẹ kakiri, sibẹsibẹ gbogbo ayọ wọnyi ko ti i to ayọ Ajinde paapa. Kini ayọ Ajinde paapa? Eyi ni ki a le jinde pelu Kristi nipati ẹmi saaju akoko ajinde ti ara lẹhin iku.

Ki a to le jinde si iye ainipẹkun nipa ti ẹmi, a ni lati kọ gbogbo ẹṣẹ wa silẹ. Iwa ẹṣẹ, iwa oju kokoro, iwa ole, iwa booba o pa, booba ki o bulẹṣẹ, iwa adiẹ dami loogun nu, ngo fọ li ẹyin, gbogbo iwa wọnyi ati awọn miran ni a ni lati kọ silẹ, ki a tẹle apẹrẹ iwa Mimọ ati iwa ifẹ ti ẹniti iṣe akọbi ninu awọn oku, a ni Jesu Kristi.

Ẹ ranti pe awọn mejila ni ọmọ ẹhin Jesu Kristi; ṣugbọn Judasi Isikariotu ṣe oju kokoro owo o si di ẹni egun, iba san fun un ki o mu wa s'aiye rara ju adanu ajinde si iye ainipẹkun ti o fi ṣere jẹ lọ nipa oju kokoro.

Paulu Apọsteli sọ fun awọn ara Kọrinti wipe, "Bi o ba ṣe pe ko si Ajinde Oku, asan ni igbagbọ wa" Jesu Kristi si tun kilọ fun awọn Ọmọ ẹhin rẹ pe, ki nwọn ṣọra nitoripe "Ki iṣe gbogbo awọn ti npe mi ni Oluwa, Oluwa ni yio wọle Ijọba Ọrun, bikoṣe kiki awọn ti o ba nṣe ifẹ Baba mi ti mbẹ lọrun,"

O yẹ ki a mọ daju pe ajọyọ ajọdun yi ko le fun wa ni iye ainipẹkun bikoṣe pe ki a kọ gbogbo awọn ẹṣẹ wa silẹ, ki a si wa tele ẹkọ Jesu pe, ki a fẹran Ọlọrun ju ohun gbogbo miran lọ ati pe ki a si fẹran Ọmọ nikeji wa gẹgẹbi ara wa.

"Jesu jinde, o si di akọbi ninu gbogbo awọn ti o sun. "Jesu Kristi ni ẹnikini ti o kọ jinde kuro ninu oku on na si ni Oluwa Ajinde fun gbogbo awọn oku.

Ẹnikẹni ti ko ba ni Ajinde kuro ninu ẹṣẹ nipa ironupiwada ati igbagbọ ṣaju iku ti ara, ki yio le ni Ajinde si iye ainipẹkun bikoṣe si ijiya ainipẹkun ni Ọrun apadi lẹhin iku ti ara.

Ki Ọlọrun maṣe jẹki gbogbo laala wa jaṣi asan ki a si le jere iye ainipẹkun lẹhin iku wa, nigbati ao fi aiye osi ati ẹṣin yi silẹ, ti ao si da gbere fun aiye pe-o digboṣe, ki a le fi ayọ kọrin na pelu awọn Mimọ l'Ọrun pe:

"Kabọ ọjọ rere," l'ao ma ni titi:
A ṣẹtẹ 'ku loni, Ọrun di tiwa.
'Wọ oku d'alaye. Ọba titi aiye,
Gbogb' ẹda Rẹ Jesu, ni nwọn njuba Rẹ'
"Kabọ ọjọ rere," l'ao ma wi titi, A ṣẹtẹ 'ku loni,
Ọrun di ti wa.

Ẹ ku ọdun, ẹ ku iyedun, A ṣeyi ṣ'amọdun o.

# Igbẹhin L'oju

Lati ọwọ AFỌLABI ỌLABIMTAN

Bọdalẹ nla tolotọo nta raka.
Kolotọ farabalẹ, ki o sa fi iyedenu
Tori ibẹrẹ kọ loniṣẹ, igbẹhin lọran
Ọjọ abaku la mọ paiye yọ ni
Igbẹhin loju, ka sa mọ kanju
Bosiki npawo, bo ninu re nkuta
Ko ma banujẹ, igbẹhin lalayo ota
Eni buru bi awusa ẹni re bi ewuro
Awusa afakọkọ loyin, a fi gbẹhin koro
Ṣe igbẹhin ladun ewuro
K'ọjọ alẹ to san wa ju to wurọ lọ
Iyẹn ni atata ọrọ
Iwọ ọga agaba ti ngba riba koto fun ni nişẹ
Iwọ akọwe agba ti ngbo wo lọwọ alaini
Ko to ba wọn waṣẹ ati se
Edumare a dakẹ dẹjọ Oluwa
Ọba oke ko ni pin iku si bi kan o daju
Ki agbe osika lakọkọ, ṣugbọn atisun lẹbọ
Iwọ agba onigbagbọ to ndaju lọsẹ ọsẹ
Ranti iye riba to nda koni ere
Owo eru, ibi airoju lo nko ba ni
Iwọ Imale ladani to nba wọn di tira
Gbogbo saka rẹ ṣe otuwa ni
Ṣe igbẹhin loju
Ka lowo lowurọ, talaka lalẹ
Iyẹn ko ni iye ẹni
Bo lagbara loni bo nfiya jẹ mẹkunnu
Bo lowo lọwọ lo njẹ ara yoku ni iya
Ranti pe igbẹhin loju
Ẹda ti ko yi ti ku ko kọ ja ohunkohun
Ẹgọrọ oṣelu lo nfi oro sinu ṣelu
Nwọn abu owo onipo nla fun ẹni wọn ko fẹ
Nwọn a ge ti ẹni jẹ ti wọn silẹ rẹpẹtẹ
Ṣugbọn eni gbingi oro saiye nkọ
Bo pẹ titi igi a so
Bi haba ko le duro
Abọ sọwọ ọmọ, ọmọ a si jiya eṣẹ
Ika iba ma ro igbẹhin, bawo ni i ba ṣe dun to o
Oninu buburu iba maro ọla
Ṣe aiye i ba ma yẹ gbogbo wa
Iwọ baba agba to nbori ọmọ ọlọmọ jẹ
Ranti po bimọ funra rẹ
Ko ma ni lọ ko ma bọ o daju
Bi ko de loni, a de lọla abọ lọran
Igbẹhin loju
Ka sa mu suru ka fiyedenu
Atore ati ikankan ki i gbe
Iṣu ko ni ta ekurọ odaju
Ohun a ba gbin la o ka gbangba.


AH! REMEMBER THAT

**The Social Dandies**

*PRESENTS*

**An Eid-Ul-Kabir Dance**

AT

**FORESTER CENTENARY HALL**

22, Ọdunlami Street, Lagos, On Sunday 26th April 1964 (Sunday Ọdun Ileya) at 6 p. m. till dawn

*Music by one and only*

NEW TIME TAPE RECORDING
BASHY & HIS YOUNG STARS ORCHESTRA

Ladies and Gents, seize this opportunity and come and listen to the latest beats of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo M. B. E., Broadway Dandies of Ghana on the New Time Recording Enterprises and Bashy & His Young Stars Orchestra. Be there in time to avoid rushing.

**Tickets: 4/- Flat**

Tickets now on sale at 3, Olushi Street Lagos 16, Bamgboṣe Street, Irohin Imọlẹ Officess Wẹmimọ Alakija 41 Denton Street, Ebute-Mẹtta.




Our tradition is based on principles of lasting validity. Quality in every detail, true craftsmanship applied to most advanced production methods, safety and elegant styling. The scrupulous application of these principles in the design and manufacture of all Mercedes-Benz products is manifest in the product's performance and beauty. Mercedes-Benz vehicles of today are the embodiment of a 75-year tradition of progressive development in every sphere of car design and production.

**MERCEDES-BENZ**



DON'T FORGET THAT YOU CAN ALSO **TRADE IN** YOUR OLD MERCEDES-BENZ OR RENAULT CAR!

# LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.

# HA ILE IGBOMINA

Ha ! Ilę Igbomina !
Lojojumo ha ko ni mo nro
Tianfani inu re !
Gbogbo ọmọ Rẹ t'o nfe Q
Ni yio şe rere.
Iwọ ti nsun Oyin ati
Wara jade.
Fun anfani awọn ọmọ inu
rẹ
Ki awa ma ba ku iku ęsin
ati iku oro !
Ki araiye ma ba fi wa şę-
lęya

Gbe Oloto, Olori ati Ala-
kikanju jade fun wa!
Qmọ ti ędun wa yio jęęun
rẹ, ti ko ni je arọie yo,
Iru omo ti yio ka ire Ilę
Igbomina si.
Ju ohun oro aiye lo
Iru ọmọ ti yio wa isimi
fun wa.

Iru ọmọ ti awọn pęganpę
gan yio wa pri lakoko rę
Iru ọmọ ti yio jẹ onifę oni-
rẹlę ologbọn; ọmọ onişuru
Iru ọmọ ti kokoro owo ko
ni le wọ oju rę Omo ti yio
le so bayi wipe

"Ha ! Alaię Igbomina bi
mo bagbagbe rę !
Bi emi ko ba si fi ire ile
Igbomina şiwaju gbogbo
oyo mi,
Ki ahọn mi le mọ erigi mi
Ki owo ọtun mi paapa s
gbagbe ilo rę"
Iru eniti o ba le sọ bayi
temiletmi,
T'o si le fi şewahu
Lati ibere d'opin, nitoripe,
Ibere kişe onişę,
Iru eni bę lo le jafani ile wa

---

## ★ YE IRAWO RE WO ★

AQUARIUS (Jan. 20 -Feb 18) O jẹ ohun ti o ma nwu ọ lati parọ okan, bi o ba fę se bę, eyi ni akoko na ti o dara lati şe. Ire ni yio si ja si fun ọ loni.

PISCES (Feb. 19 - Mar. 20) Oni li ọjọ ti o dara lati pari edeaiyede kan ti o ti nda ọ lamu, iwọ yio si ba wọn se apejọ titun kan loni, nibę ni iwọ o ti ri aye sọ- rọ ędun ọkan rę jade.

ARIES (Mar. 21 - April 19) O tọ ki o fi si ero nipa ọrọ awọn ębi rę iwọ yio ri pe, gbogbo awọn ọrę ati ojulumọ rę lo şe tan lati ran ọ lowọ loni.

TAURUS (April 20 - May 20) Ojọ oni ko dara lati yanju ọro, nwọn o si pari ija larin iwọ ati ọmọbinrin kan lọjọrọ ti oni, bi nwọn ba da ọ lębi, maşe ko,

GEMINI (May 21-June 20) Şe suru pupọ loni ohun gbogbo yio si yọri si rere, nwọn o pari ọrọ owo kan larin iwọ pęlu ęnikan ohun gbogbo yio si ma yọri fun ọ si rere.

CANCER (June. 21-July 20) Sọ asọye ọro rę ki o han ketekete ki osi yanju ọpọ enia lo nfe şe iranlọwọ fun ọ Bi o ba ngbero lati losi ajo ọjọ oni dara lati gbera.

LEO (July 23-Aug 22) Nınu ohun kohun ti o ba nşe rarti kio maşe gbagbe nipa işe rę Mase ... nina obinrin ... maşe ba ęnikeni ja şugbọn ma da ... kun ọrę

VIRGO (Aug 23-Sep 22) Gbogbo oro rę yio bęrę si yanju nipa obinrin Iwọ yio ni owo lọwọ o ... ati itęlọrun yio wa fun ọ Iwọ yio losi ipade ... kan loni.

LIBRA (Sept 23-Oct.23) Iwọ yio şorire loni, owo yio si ba ọ ... gohoyi ohun kohun ti nwọn ba fi lọ ọ jeki o jẹ gbogba. Iwọ yio lọ sipade atata kan loni, awọn obinrin yio ma şo mọ ọ.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Ohun kan yio mi ọ lokan, nipa iręwsi ọkan, maşe şuhun si ęni kan, obinrin rere ni iwo yio ba sọrọ loni, ti eba şe adehun, maşe yę adehun na.

SAGITTARIUS (Nov.23-Dec 22) Ọro kan yio şęlę ni şişe, yio si pari daradara. Ayipada yio han lọdọ obinrin ti o ti mba sọrọ ri, iwọ yio si ri ęhun kan gba laro tęlę loni, sugbọn şo ọrọ ti yio ma a jade lenu re.

CAPRICORN (Dce 23-Jan.19) Ojo oni dara bi o ba fę sipa pada ma şe tęki işe pọju fun o, ohun ti o dara fun ọ nipe ki o wa isimi fun ara rę, nitori ai san ojiji.

---

BERE OJUOWO EGBOGI AWỌN FARANŞE TI NWỌN NPE NI-

# RICHELET

Eleyi yato patapata si awọn Rọbi-rọbi. Işę rę lara enia si daju fun Iwosan gbogba Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ĘJĘ ARA' bi Mọn mọnọ

FUN ARUN ĘJĘ ARA ENIA GBOGBO




Meji rę ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ęje ti nwọn si nta kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilę ko di owo Iyen şe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yęn rara tabi ti nwọn npo ta ni ilę yi.

Gęgębi awọn Onibara wa ti mọ irufę awọn egbogi ba wọn yęn a ma a ba ojuowo egbogi atata ti a ranşę fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Iatambulu si Itali jẹ.

Mọ daju pe, bi ęję ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju şuşu tabi didun, Jędijędi Akọ ba, arun Ędọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa, Egbo-Ęsę Amodi Apo ile itọ, ęhin didun tabi ibaradi riro pęlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa ninu ęję ara rę patapata yio si fọ ęję rę mọ toritoni pęlu.

Şa dan igo rę kan wo iwọ yio si ma a rohin rę fun ęlomiran pęlu.

Bere egbogi aejbina Peyal yi ni şọbu wọnyi:—
Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phore: 22878 Nigeria, (Oja Ita Fai)

---

# Akiyesi

Ęnikeni ti oba mọ itan awọn Ọba ilę Yoruba iba şe eyiti o ti ku ri tabi eyiti oşi wa laaiye tabi bi nwọn ti şe tę ilu kọọkan do tabi eyikeyi ninu Itan Işędalę Yoruba, ki oluwarę kọ ọ sọwọ.

Ao si tę jade fun anfani gbogbo enia. Ę maşe gbagbe itan Işędalę nitori awọn ọmọ wa.

Ę işękuo.

OLOTU

---

# Iwọ Ha Nlọ Si Mekka Ni Ọdun Yi Bi?

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA"
MO JĘ RI O. OLUWA MO JĘ IPE RĘ
Enikeni ti o ba fę lọ si "MĘKKA" Ilu Mimọ ni ọdun yi gbodọ ni iwe
"AFINIMONA NPA ISIN HAJI"
LOWỌ KI OLUWARĘ MA BA ŞINA TABI NA OWO INAKUNA. KI O LE LỌ ALỌBỌ MĘKKA NA DADA
t'Oluwa jọwọ se Isin Haji wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ un wa ni rere ti aiye ati t'ọrun Oluwa wa, ki o sisọ wa ni bi iya nitori IWỌ NI ỌBA alagbara Oluori gbogboęda patapata" Amin.

## "WAS SALAM"

*AKIYESI* Gbogbo Musulumi Ododo ni oyę ki o ni iwe na lọwọ nitori igbati yio ba fę lọ si MĘKKA
*Iye Owo 5/6, £3 fun dosini*
MANAGER
N2/99 SHITTU STREET
Ibadan

# Eyi ni awọn ọjọ Ọja Ilẹ Yoruba

## ỌJỌ AJE MARCH 23 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo, Ejinrin |
| ABEOKUTA | Ijoko, Bẹrẹkodo, Aşu, Watinmi, Owode |
| IBADAN | Akeroro, Idọfin, Lagun Şagbẹ, Ogunjau, Mọlete, |
| IJEBU | Aiyepe, Shegamu, Itaoşu, Ogere Irolu, Itẹle, Ode-Rẹmọ, Oyingbo |
| IJESHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imẹsi-Ile |
| EGBADO | Alagba, Ilaro, Ọja-Ọdua, Sunwa Iboro, |
| EKITI | Ilogbo, Ishan. |

## ỌJỌ IṢẸGUN MARCH 24 (TUESDAY)

| ILU | ILU |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun-Eko, Ojuwoye |
| ABẸOKUTA | Atan Agbado, Ifọ Itori, Itoku Fabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila, |
| IBADAN | ẹdẹgbọ, Oyedeji, Ogburo, Ẹgbẹda, Babalokuta, Ijaiye Orile. |
| IJẸBU | Ilishan, Isara, Imodi, |
| JẸSHA | Ẹpẹ, Ilọba, Imuroko, E-inmọ. |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado-Oda. |
| EKITI | Egosi, Odo-Aiyedun. |

## ỌJỌ'RU MARCH 25 (WEDNESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin, Badagary |
| ABẸOKUTA | Ọtta, Abalabi, Sodẹkẹ, Omida Ilawọ |
| IBADAN | Ituko, Sojukonkọ, Tọwọbowo Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Ọkun—Ọwa, Ẹruwọn, Omu. Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila Ijọun, Imasai Owode |
| EKITI | Oke-Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ ỌJỌBỌ MARCH 26 (THURSDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ikẹja,Agege, Ebute-Ero Ọjọ Ajido |
| ABẸOKUTA | Lafenwa, Ọbada, Ọba, Kajọla Ajegunlẹ, Idọgọ Olodo |
| IBADAN | Lalnpọn, Ajegunlẹ Owode Igbo-Ọra |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Işara, Imodi |
| IẸSHA | Iwara, Ejiro, Odo, Ibokun, Ijẹbu-Ijẹsha |
| ẸGBADO | Lasilo, Idiẹmi |
| EKITI | Okemesi Ifaki |

## ỌJỌ ẸTI MARCH 27 (FRIDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo |
| ABẸOKUTA | Ijoko Ibẹrẹkodo, Asu, Wasnimi, Owode |
| IBADAN | Akẹroro, Idọfin, Lagun, Sagbẹ Ogunjana, Mọlete |
| IJẸBU | Aiyepe, Sagamu, Itaosu, Ogere Irolu, Itele, Ode-Rẹmọ |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode Kajọla, Imẹsi Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilaro, Ọja-Ọdan, Sunwa, Iboro |
| EKITI | Ilogbo, Ishan |

## ỌJỌ ABAMẸTA MARCH 28 (SATURDAY

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun-Eko, Ojuwoye,Ikosi, Ẹp |
| ABẸOKUTA | Atan, Agbado. Ifọ, Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila |
| IBADAN | Fẹdẹgbọ, Oyedeji, Ẹgbẹda, Baba okuta' Ijaiye-Orile |
| IJẸBU | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imọpe sara, Imodi, Ishan, Akẹsan, |
| IJẸSHA | Ẹpẹ. Ilọba. Imuroko, Erinmọọ Ilaşẹ, Iperindo |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado-Odo |
| EKITI | Egosi, Odo-Aiyedun |

## ỌJỌ AIKU MARCH 29 (SUNDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin |
| ABẸOKUTA | Ilaa, Abalabi, Sodẹkọ Omida Itwọ |
| IBADAN | oko, Şojukonko Tọwọbowo Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnẹ, Ọkun-Ọwa Ernwọ Omu Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo Idoko Iloko |
| ẸGBADO | gbogila, Ijọun, Imasai, Owode |
| EKITI | Oke—Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ AJE MARCH 30 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | kẹja, Agege |
| ABẸOKUTA | Lafẹnwa, Ọbada, Ọba, Kajọla Ajegunlẹ, Idọgọ, Olodo, |
| IBADAN | Lalupọn, Ajegunle, Owode Igbo-Ọra |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Işara, Imope |
| IJẸSHA | Iwara Ejiro, Odo, Ibokun Ijẹbu-Ijẹsha |
| ẸGBADO | Lasilo-Idiẹmi |
| EKITI | Okemẹsi, Ifaki. |

# IROHIN KAKIRI AGBAIYE

Lati Ọwọ EJON' GBORO

### ONITŞHA

Ẹgbẹrin 1000 awọn ọmọ Ibo ti Ijoba Ipinle Ariwa le kuro ni Kaduna ni nwọn ti de si Onitsa nwọn pẹlu awọn ẹbi wọn.

### KADUNA

Ọgbẹni Luke Ejinkeoniye ni o ti pe Ijọba Ipinlẹ Ariwa lẹjọ pe ki nwọn o san egbẹdogun pọnun (£3000) fun on nitoripe Ijọba fi ipa gba ile on ni Kaduna nitori aba yọri eto ikania.

### CAPE-TOWN

Ọgbeni Carste, Minist‹ alamojuto eto işẹ idajọ sọ fun ipade Ile Igbimọ pe Ejileladọsan (172) awọn ọlọpa ni nwọn ti wẹwọn larin ọdun 1960 - 1963 nitoripe, nwọn huwa ti ko dara si awọn ara ilu, o ni oyinbo mọkandinlọgọ ni o wa ninu wọn awọn yoku si jẹ enia dudu.

### YABA

Jinnijinni dabo gbogbo enia nigbati mọto ayọkẹlẹ kan LF 7296 kọlu onibasikulu kan niwaju ọja Sabo ti onibasikulu na si ku bamubamu lojukanna

### ILUBINRIN

Idaamu nla ba gbogbo enia nigbati ina nla kan şẹlẹ larin ọja Ilubinrin Eko ti gbogbo awọn ero si tuka ki awọn panapana o to wa pa ina na

### ỌBALENDE

Awọn ọlọpa ti mu ole kan ti o wọle lọ ko ẹru ọgbẹni Mọşhudi Olumọşe. 1, Ajeniya Street, iye owo awọn ẹru na jẹ £14: 4/-

### EBUTE MẸTTA

Awọn Ọlọpa ti o nsọ ọgba reluwe ti mu okunrin kan, ti o sọkalẹ ninu ọkọ reluwe ti on nikan si gbe Basikulu meji J. 4978 ati B. 29931 lowọ.

### APAPA

Ọdaran kan ti o gba oju ferese wọle lọ ko ẹran ni nọmba 1, Sapelẹ Road ni awọn ọlọpa ti mu, asi lero pe yio de iwaju adajọ ni owurọ yi lati sọ ti ẹnu rẹ

### YABA

Ariwo ta ye nigbati awọn mọto meji kan, LH 3784 ati LH 7989 forisọ ara wọn ti ọkunrin si farapa ninu ijanba na.

IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBO GBO LAWA

No. 567 MONDAY MARCH 30, 1964 (2D)

## Akiyesi Pataki Fun Enia Gbogbo

Lẹhinti mo ti ṣe abẹwo kakiri Ilẹ Naijiria ati Ghana, o dabi ẹnipe ọpọlọpọ enia ni nwọn nro wipe Iwe Irohin Imọlẹ ati Iwe Irohin Akintọla ti nwọn npe ni Imọlẹ Owurọ ọkan na ni Iwe mejeji.

Eyi ki iṣe bẹ rara asi fẹ fi ye gbogbo enia ki o ye wọn wipe gedegbe ni Iwe Irohin Imọlẹ daduro ko faramọ ẹgbẹ oṣelu kankan ko si ni ohunkohun ṣe pẹlu Imọlẹ Owurọ.

Iwe Irohin Akintọla ti nwọn ntẹ ni Ibadan ni o ngbẹnuṣe fun ẹgbẹ Akintọla Ibadan ni nwọn gbe ntẹ Imọlẹ Owurọ, Eko ni a gbe ntẹ Iwe Irohin Imọlẹ lati ọdun meje (1957) sẹhin.

Ao ṣe ifilọ yi lori Radio fun gbogbo enia lati gbọ, ṣugbọn ẹniti o ba tun fẹ alaye lori ọrọ yi le kọwe tabi ki o wa ri Alakoso Ile Iṣẹ Irohin Imọlẹ ni nọmba

16, BAMGBOṢE STREET,

PHONE 21985, LAGOS.

# ẸGBẸ AFẸNIFẸRE MUSHIN KỌ ẸGBẸ DẸMỌ

MUSHIN:— Irohin ko to afojuba ni ipade ti awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ọdọ ṣe ni nọmba 23, Awoyọkun Street, Mushin ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu yi labẹ Alaga Ọgbẹni N. A. Oyeṣile ni deede agogo mẹrin abọ.



OLOYE ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

Ki ipade na o to bẹrẹ ni awọn obinrin lọja Mushin Kajọla Alade, Ọlaleye, Oshodi ti bẹrẹsi jo yipo ka kiri ilu ti awọn ọlọja ti nwọn patẹ si oja ati awọn ti o wa ninu ile si nsare pa lẹmọ ti nwọn si ntẹle awọn obinrin na.

Bi awọn obinrin Ọlọpa na ti nlọ ni nwọn nkọ orin orişirişi ni ọkan ko jọkan ti awọn enia si nkigbe Awo! Awo!! Awo!!! ni gbogbo adugbo ti nwọn ba de.

Ṣugbọn nigbati o di deede agogo mẹrin ni ẹsẹ gbogbo awọn obinrin ọlọja na ati awọn enia sarakisaraki ninu ẹgbẹ Afẹnifẹre ti pe samusamu sinu ile na.

Nigbati ipade na bẹrẹ aga ijoko dosinni mẹrindinlogbọn ti nwọn tọju silẹ, fun awọn enia na ko to wọn lati joko rara, nwọn si tun sare lọ ko aga wa ni adugbo fun ọpọlọpọ awọn enia ti nwọn ko ri aye joko.

Nigbati ipade na bẹrẹ, ni Ọgbẹni N. A. Oyẹsile ti iṣe alaga ẹgbẹ Afẹnifẹre ọdọ ni Mushin dupẹ lọwọ gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na fun wiwa ti nwọn wa si ipade na

O tun dupẹ lọwọ gbogbo awọn obinrin ọlọja ti nwọn wa si ipade na, o si tun ki wọn fun pe nwọn le fi iṣẹ ati ọja wọn silẹ lati wa si ipade na.

Lẹhin ti o ti dupẹ tan ni o wa ṣe alaye fun gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na pe, ohun ti o mu on ti on fi pe ipade na ni ọrọ kan ti on gbọ lori ẹrọ Redio ti Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria pe, "gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre Mushin ni nwọn ti di ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ N. N. D. P.) eyi ni ẹgbẹ titun ti nwọn ṣẹṣẹ da silẹ.

Ọgbẹni Oyesile tun fi ye gbogbo ile wipe, ko si ẹniti o nṣe ẹgbẹ Dẹmọ (N. N. D. P.) ni gbogbo ilu Mushin afi bi awọn ti ṣe gbọ lati ori ẹrọ Redio (W. N. B. S.) wipe gbogbo awọn ara Mushin ti iṣe ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ni o ti nṣe ẹgbẹ na nisisiyi.

Ọgbẹni T. A. Beecroft ti iṣẹ akọwe agbaẹgbẹ na fi ye gbogbo ile wipe, gbogbo ti awọn ngbọ lati ori ẹrọ Redio wipe, "Awọn ọba kan ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ti darapọ mọ ẹgbẹ Dẹmọ, ki iṣẹ otitọ, o si jinna si ododo."

Ọgbẹni Beecroft sọ fun awọn ọmọ ẹgbẹ wipe bi awọn ti gbọ ti awọn lori ẹrọ-asọrọmagbesi, ti o si jẹ iyalẹnu fun awọn, o ni bẹ ni awọn ọba ati ijoye ngbọ ti wọn na lori ẹrọ-asọrọmagbesi, ti ọrọ na si nya wọn lẹnu, sugbọn ẹru mba wọn, ni ko jẹki nwọn o le sọrọ.

O ni ọba ti o ba sọrọ pe on ko faramọ ẹgbẹ Dẹmọ, o ni Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ko kọ lati le ọba bẹ kuro lori itẹ.

O tun ṣe alaye siwaju pe, ti ọba kan ba kọ wipe on ko faramọ ẹgbẹ titun na, o ni nwọn o rọ ọba na loye lọsan gangan ni.

Lẹhin ọpọlọpọ alaye, ọgbẹni Beecroft tun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ wipe Nitoripe ọba Alaiyeluwa Adebọwale ọba Iṣẹyin ko fara mọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ni nwọn ṣe le ọba na kuro leri oye

Nigbati wọn o si gbe ọba na, nwọn ko gbe lọ si arin ilu latin awọn enia, sugbọn nwọn gbe e lọ si ebute oko kan ni Okitipupa.

O ni bi ọrọ ti awọn gbọ lori ẹrọ asọrọmagbesi Ipinlẹ Iwọ Orun ti ṣe jẹ ohun iyalẹnu fun awọn, nitoripe ọrọ na ki iṣe otitọ, bẹna ni irohin nkan awọn ọba ni ojiji, sugbọn ko si ọkan ninu awọn ọba ti o le sọ pe ọrọ ti on gbọ lori ẹrọ asọrọmagbesi ki iṣe otitọ.

Lẹhinna ni gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na wa fihan nipa igbọwọ soke wipe, awọn ko faramọ ẹgbẹ Dẹmọ.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na si tun ṣe ileri wipe, a... won ki yio ṣe ẹgbẹ Dẹmọ ni Mushin ...-lai.

### IPINNU ẸGBẸ

Awọn ọmọ ẹgbẹ na wa ṣe ipinnu wipe bi igi ba nọn igi mọ igi, awọn ko ni fi ẹgbẹ Afẹnifẹre silẹ ati pe gbọning-bọnin ni awọn yio duro lẹhin ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ti iṣe Olori ẹgbẹ na.

Iya afin Lawal sọ fun awọn ọmọ ẹgbẹ na wipe ki wọn o maṣe foju si ohunkohun ti o ba le de si wọn loni.

O tun ṣe alaye pe nigbati Oloye Awolọwọ fi nlọ si ọgba ẹwọn o fi ye gbogbo aiye pe on nlọ lati inu imọlẹ si inu okunkun biribiri, ṣugbọn lẹhin okunkun, imọlẹ mbọ wa lẹhin ọla, nigbati ọmọ enia yio bọ sinu ọla na rẹ.

Ninu awọn enia ti o wa ba Ipade na sọrọ ni Ọgbẹni Bisi Ọnabanjọ, Ọgbẹni J. A Ọdẹku, Oloye Lawal, ti gbogbo aiye mọ adapẹ orukọ rẹ ni "ỌMỌ PUPA" Mushin.

Alhaji Busari Obisẹsan, Olu. Ọdunjọ, Alhaji Adegbenro Oloye Akin-Olugbade ati awọn miran ti aye ko si lati da orukọ wọn.

Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgboṣe Street, Lagos Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M.S. Grammar School) P. O. Box Bariga (30/3/64)